**YORUBA NOTE:**

**CLASS: J.S.S 1.**

**KOKO – ISE**:

Kinni leta kiko? Eyi ni aroko to je mo kiko leta si enikeji. Bakan naa ni a tun le so wipe . Leta kiko je ona ti a n gba ko ero inu eni sile lori ohun kan ranse si elomiran bii ore, obi, ijoba,tabi Oga ile-ise kan.

Orisii leta meji lo wa. Awon ni.

(i) Leta Gbefe (Informal Letter). Eyi ni leta ti a ko si Ore eni tabi ebi eni. O le je Baba, Iya, Egbon ati Aburo eni.

(ii) Leta Aigbagbefe. (Formal Letter). Eyi ni leta ti a ko si eniyan to wa ni ipo kan lenu ise bii: Oga ile-ise ijoba , Oga ile-iwe tabi leta iwase abbl.

1. Adiresi Akoleta.

35, Ota- road,

Ikorodu.

Lagos.

3/4/2020

ii. Ikini ibere: Oruko tabi apejuwe en ti a ko leta si. B.A

Yewande mi tooto. Tabi Baba mi tooto.

iii. Koko inu leta: Idi ti o fi ko leta naa

iv. Ikini ipari/ idagbere: Emi ni ore re .

Tayo Tabi Bola.

**ISE-AMURELE: J.S.S.1 (ASSIGNMENT)**

1. Kinni leta kiko?
2. Kinni leta Gbefe?
3. Daruko awon igbese ti a n gbe ni kiko leta gbefe

**YORUBA NOTE.**

**CLASS: J .S .S. 2**

## KOKO-ISE:

Yoruba gba pe enikan wa ti o ni ogbon, agbara, ti o ga ju gbogbo orisa ati eda aye lo. Won gbagbo pe ohun ni alakoso orun ati aye. Oun ni o da aye ati awon eda inu re. Awon Yoruba gbagbo pe won ni lati maa I oruko olorun si ohunkohun ti won ba n se.

**Igbagbo awon Yoruba**: Ninu Asa Yoruba, eni owo ni oba je. Idi niyi ti won fi fun olorun ni oruko oba gege bi owo ti won ti won ni fun un. Eyi ni won fi n pee ni Oba awon oba, oba orun, oba Airi, Oba iyanu. Ii.Won gbagbo pe Olorun ko pe meji . Okan soso ni. Eyi niwon fi n kii ni okan soso ajanaku tii migbo kijikiji.

iii. Won gbagbo pe Olorun kii ku, kii saisan. Idi niyi ti won n so pe Oba aiku, Oba Aisa, Oba Aidibaje.

iv. Won tun gbagbo pe Alaanu ati onidajo ododo ni Olorun. Eyi ni won se n kii pe Ako-ma-tika-leyin . A duro gboingboin leyin asooto.

Lara Awon oruko miiran fun olorun ni:

Olorun: Olu orun tabi eni to ni orun.

Olodumare: Eyi ni ohun ti o tobi julo

Aterekari aye: Eni ti agbara ati ola re kari gbogbo aye. Ko si bi to gba titobi re.

Adedaa, Asedaa, Adedaa: Oun ni o da ohun gbogbo ni orun ati aye.

Di e ninu oruko to fi agbara ati titobi Olodumare han, B.A. Olu-orun, Olugbala, Oludande, Eleburu-ike, Oga-ogo, Adakedajo, Alagbara giga abbl.

Awon Yoruba kii fi oruko Olorun pe awon orisa. Olorun ni Olorun n je. Olorun ni o da awon orisa. Alarina tabi onigbowo ni awon Yoruba ka orisa si.

**ISE- ASETILEWA: (Assignment) J.S.S. 2**

i. So itumo awon oruko Olodumare gege bi o ti han ninu igbagbo Yoruba?
ii. Daruko orisii oruko ti awon Yoruba n pe Olodumare Mewaa?